**Ọjọ́ kọkàndínlógún (19th) Oṣu kẹrin ọdún 2022**

# KOFID-19 àti àwọn ilé-ìwé

## Àwọn òbí/àwọn alábòjútó Olùfẹ́

## IMÚDÓJÚÌWỌ̀N LÓRÍ ÒPIN ṢÍṢE ÀYẸ̀WÒ KÒRÓNÀFÁÍRỌ̀SÌ LỌ́FẸ̀Ẹ́ ÀTI ÀWỌN ÌTỌ́NISỌ́NÀ TITUN

Ní títí di ọjọ́ ìkíní (1st) Oṣu kẹrin, Ìjọba kò pèsè àyẹ̀wò kòrónáfáírọ̀sì (KOFID-19) lọ́fẹ̀ẹ́ mọ́ fún gbogbogbò ní Ìlu-Ọba (England). Èyí ní níní ààyè sí àwọn àyẹ̀wò fún àwọn ilé-ìwé, ilé-ìwé jẹ́lé-ó-sinmi àti àwọn ilé-ìwé àkànṣe nínú. Àwa ńkọ̀wé láti jẹ́ kí o mọ̀ ohun tí ìtọ́nisọ́nà titun túmọ̀ sí fún ọ àti àwọn ọmọ rẹ, ní ìbámu sí àkóso àkòràn nínú àwọn ilé-ìwé àti àwọn ìṣètò ọdún ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀.

## Dídín títànkálẹ̀ KOFID-19 kù

Àwọn ilé-ìwé àti àwọn ètò yóò tẹ̀síwájú pẹ̀lú àwọn ìlànà láti dín títànkálẹ̀ KOFID-19 àti títànkálẹ̀ àwọn àrùn mìíràn kù – tí ó ní lílọbíbọ̀ atẹ́gùn àti lílo àwọn ààyè tí ó wà níta nínú, ríri dájú wípé àwọn ènìyàn fọ ọwọ́ wọn déédé, lo pépà ìnùwọ́ àti sísọ wọ́n nù ní ọ̀nà tí ó tọ́.

Jọ̀wọ́ rán ọmọ rẹ létí láti wúkọ́ sínú pépà ìnùwọ́ tàbí sí ìgúnpá wọn, bo ẹnu àti imú wọn pẹ̀lú pépà ìnùwọ́ kan, (kìí ṣe ọwọ́) nígbàtí wọ́n bá wúkọ́ tàbí sín, àti láti fi àwọn pépà ìnùwọ́ tí wọ́n lò sínú ilé-ilẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀. Béèrè lọ́wọ́ wọn láti fọ ọwọ́ wọn pẹ̀lú ọṣẹ àti omi lóòrèkóòrè, pàápàá ṣáájú kí wọ́n tó jẹun, àti láti lo ohun ìfọwọ́ apakòkòrò bí ọṣẹ àti omi kò bá sí.

## Ṣé ọmọ rẹ le wá sí ilé-ìwé?

Fún àwọn ọmọdé àti ọ̀dọ́ tí ọjọ́-orí wọn jẹ́ méjìdínlógún (18) àti tí ó kéré, KOFID-19 ní ọ̀pọ̀ ìgbà jẹ́ àìsàn kan tí kò nira tí ara ọ̀pọ̀ sì máa ńyá ní àwọn ọjọ́ díẹ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ wípé àyẹ̀wò kò sí mọ́, kí àwọn ọmọdé àti ọ̀dọ́ dúró sílé kí wọ́n sì dín níní ìfarakínra pẹ̀lú àwọn ènìyàn mìíràn kù bí wọ́n bá ní àwọn àmì àìsàn KOFID-19 (àkójọ lẹ́kùnrẹ́rẹ́ wà n'ísàlẹ̀*) **àti**:

- ní ìwọ́n ooru gíga tàbí
- ara wọn kò yá tó láti lọ sí ilé-ìwé, girama tàbí ilé-àbójútó ọmọdé, tàbí ṣe àwọn ohun tí wọ́n máa ńṣe déédé.

Wọ́n lè padà sí ilé-ìwé, girama tàbí ilé-àbójútó ọmọdé nígbàtí wọn kò bá ní ìwọ̀n ooru gíga mọ́ tí ara wọ́n sì yá tó bẹ́ẹ̀ láti wá.

Àwọn ọmọdé tí wọ́n ńyàgbẹ́ gbuuru àti/tàbí ńbì kò gbọ́dọ̀ wá sí ilé-ìwé títí di ọjọ́ méjì (wákàtí mèjìdínláàdọ́ta (48)) lẹ́yìn tí wọ́n ti bì tàbí yàgbẹ́ gbuuru, **pàápàá bí wọn kò bá ní ìwọ̀n ooru tí ó ga kan**.

Láti ọjọ́ ìkíní (1st) Oṣu kẹrin, ẹnikẹ́ni tí ọjọ́-orí rẹ ju méjìdínlógún (18) lọ pẹ̀lú àbájáde àyẹ̀wò KOFID-19 pé ó níí gbọ́dọ̀ dúró sílé kí wọ́n sì dín níní ìfarakínra pẹ̀lú àwọn ènìyàn mìíràn kù fún ọjọ́ **márùn-ún**, ní èyí tí ó jẹ́ ìgbàtí wọ́n lè fa àkóràn fún ẹlòmíràn jùlọ.

Bí ọmọdé kan tàbí ọ̀dọ́ tí ọjọ́-orí wọn jẹ́ méjìdínlógún (18) àti tí ó kéré si bá ní KOFID-19, kí wọn kí ó dúró sílé kí wọ́n sì dín níní ìfarakínra pẹ̀lú àwọn ènìyàn mìíràn kù fún ọjọ́ **mẹ́ta**. Èyí ńbẹ̀rẹ̀ láti ọjọ́ tí ó kàn lẹ́yìn tí wọ́n ṣe àyẹ̀wò náà.

Àwọn ọmọdé àti ọ̀dọ́ máa ńsábà fa àkóràn fún àwọn ẹlòmíràn fún àkókò kúkúrú ju àwọn àgbàlagbà lọ. Bí

ara wọn bá yá tí wọn kò sì ní ìwọ̀n ooru lẹ́yìn ọjọ́ mẹ́ta (3), ewu tí ó dínkù wà wípé wọn yóò tan KOFID-19 ká sí àwọn ẹlòmíràn.
Ẹnikẹ́ni pẹ̀lú àwọn àmì àìsàn tí ó mọ níwọ̀nba bíi imu tí ó ńṣe ikunmu tàbí ikọ́ tí ó mọ níwọ̀nba lè wá, ní ìwọ̀n ìgbà tí ara wọn yá tó bẹ̀ẹ̀ láti wá tí wọn kò sì ní ìwọ̀n ooru tí ó ga kan.

**<u>*Àwọn àmì àìsàn KOFID-19 lè pẹ̀lú</u>:**

- ìwọ̀n ooru tí ó ga kan tàbí gbígbọ̀n (otútù)– ìwọ̀n ooru tí ó ga kan túmọ́ sí ara ènìyàn gbóná bí a bá fi ọwọ́ kàn-án ní àyà tàbí ẹ̀yìn (o kò nílò láti ṣe òdiwọ̀n ìwọ̀n ooru rẹ)
- ikọ́ titun tí ó ńtẹ̀síwájú – èyí túmọ̀ sí wíwúkọ́ púpọ̀ fún èyítí ó ju wákàtí kan, tàbí mẹ́ta (3) lọ tàbí wíwúkọ́ gan láàárín wákàtí mẹ́rìnlélógún.
- pípàdánù tàbí àyípadà ìmọ̀lára òórùn tàbí adùn
- àìlèmí délẹ̀
- níní ìmọ̀lára rírẹni
- ara tí ó ńroni
- ẹ̀fọ́rí
- ọ̀nàfun tí ó ńdun ni kan
- imú dídí tàbí imu tí ó ńṣe ikunmu
- pípàdánù àtijẹun
- yíyàgbẹ́ gbuuru
- níní ìmọ̀lára ṣíṣe àìsàn tàbí ṣíṣàìsàn

Wíwá sí ilé-ìwé déradára ṣe pàtàkì fún kíkọ́ ẹ̀kọ́ ṣùgbọ́n ó tún ṣe pàtàkì wípé ẹnikẹ́ni tí ara rẹ̀ kò yá tàbí tí ó ṣeéṣe láti fa àkóràn láti dúró sílé. Ìwọ lè rí àlàyé NHS nípa ohun tí o ní láti ṣe bí ọmọ rẹ bá ní àwọn àmì àìsàn KOFID-19 níbí àti àlàyé síwájú si nígbàtí àwọn ọmọdé lè wá sí ilé-ìwé tàbí dúró sílé nítorí àwọn àìsàn mìíràn níbí.

Bí ìwọ yóò bá dá ọmọ rẹ dúró sílé, ó ṣe pàtàkì láti pe ilé-ìwé tàbí ilé-ìwé jẹ́lé-o-sinmi ní ọjọ́ àkọ́kọ́. Jẹ́ kí wọ́n mọ̀ wípé ọmọ rẹ kò ní wá kí o sì fún wọn ní ìdí.

## Abẹ́rẹ́ àjẹsára

### àwọn ọmọ ojọ́-orí méjìlá sí mẹ́ẹ̀dógún (12-15)

Láti ọjọ́ ìkíní (1st) Oṣù kẹrin ètò abẹ́rẹ́ àjẹsára KOFID ilé-ìwé yóò wá sí òpin ṣùgbọ́n àwọn ọmọ ojọ́-orí méjìlá sí mẹ́ẹ̀dógún (12 sí 15) yóò sì lè gba àjẹsára ní ibi ìgba abẹ́rẹ́ àjẹsára, ilé-ìtajà oògùn tàbí ibi tí ènìyàn lè wọlé sí kí ó sì gbà á. Fún ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àkójọ àwọn ilé-ìwòsàn ní Lewisham, jọ̀wọ́ wo níbí.

### àwọn ọmọ ojọ́-orí márùn-ún sí mọ́kànlá (5-11)

Láti Oṣù kẹrin, àwọn ọmọ ojọ́-orí márùn-ún sí mọ́kànlá (5-11) tí ara wọ́n yá ni a ó tún pèsè àjẹsára KOFID-19 fún ní àwọn ibi ìgba abẹ́rẹ́ àjẹsára, àwọn ilé-ìtajà oògùn, Gps àti àwọn ibi tí ènìyàn lè wọlé sí kí ó sì gbà á. Àwọn òbí àwọn ọmọ ojọ́-orí márùn-ún sí mọ́kànlá (5-11) yóò gba lẹ́tà kan láti NHS pẹ̀lú àlàyé síwájú si. Ìwọ lè kà síwájú si nípa àjẹsára náà kí o sì ṣètò ìpàdé kan níbí.

---

Àwa yóò fẹ́ dúpẹ́ lọ́wọ́ rẹ lẹ́ẹ̀kansi fún àwọn akitiyan rẹ tí ó ńlọ lọ́wọ́ láti dín àkóràn KOFID-19 kù àti dídáàbòbò àwọn ilé-ìwé wa, àwọn jẹ́lé-o-sinmi àti àwùjọ lápapọ̀.

Tìrẹ nítòótọ́,



**Angela Scattergood**
Director of Education
Lewisham Council



**Dr Catherine Mbema**
Director of Public Health
Lewisham Council